**Ọrọ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.



# Irohin Yoruba

NO. 124 WEDNESDAY NOVEMBER 11—TUESDAY NOVEMBER 17 1964 KOBO META 3D



**IPADE NLA!**

OLOYE (Iyafin) H. I. D Awolọwọ yio ṣi ipade ipolowo idibo ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA) ni Ado Ekiti ni ọjọ kẹrinla ti iṣe ọjọ Abamẹta oṣu yi.

Ogunlọgọ awọn asiwaju ẹgbẹ UPGA ni yio sọrọ nibi ipade na.

## Nipa ileri fun awọn adibo:–

# Ẹgbẹ Onikumọ p'ofo

ỌRỌ OLOTU:—

## Ẹgẹrẹmiti Jibiti [2]

YORUBA lo ma nsọ wipe "Ọpọlọ ko mọ ọna odo mọ, o da si awuruju." Bi ẹgbẹ Onikumọ parapọ—Olomi, Dọmọnu ati MDF ko ba mọ ẹtọ ti o yẹ fun wọn lati ṣe fun awọn adibo mọ, iba dara lati pa ẹnu wọn mọ lati isisiyi lọ ati titi lailai.

IWA "kaka ki eku ma jẹ sese a fi ṣe iwadanu" ti ẹgbẹ Onikumọ nhu nisisiyi gba akiyesi awọn adibo gidigidi. A ti sọ wipe ọrọ idibo ti ọdun yi ki iṣe ti ebu tabi ti iwa jagidijagan ṣugbọn eyiti aṣẹhinwa ati aṣẹhinbọ rẹ yio jẹ ti anfani fun awọn enia orilẹ ede yi ati Naijiria ti iṣe ilẹ abinibi wa.

OHUN ti a mọ ni pe ẹnikẹni ti o ba ti ṣe ohun rere silẹ tabi ti o ba ngbero lati ṣe ohun rere kan ni ọjọ iwaju ko ni gbero buburu tabi ki o dọwọ le ohun iparun. Ẹgbẹ Dọmọnu ti bẹrẹ si pa awọn enia lara, nwọn ti njo mọto onimọto kiri, nwọn si ti nhu iwa ibajẹ wọn kiri laibikita fun laakaye awọn adibo.

YORUBA bọ-nwọn ni onisẹ ki ifẹ ki Iṣẹ on bajẹ loju on. Bi ti ẹgbẹ Dọmọnu kọ. Iṣẹ wo ni ẹgbẹ Akintọla ṣe silẹ ti ko ni fẹ ki o bajẹ loju on. Iwa ipalara ti nwọn nhu bayi ti fihan pe nwọn ko ni ohun rere kan ni ipamọ fun awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun ni pataki ati Naijiria ni apapọ.

A TI sọ tẹlẹ pe ko si ohun rere kan ti o wa ninu ileri ti ẹgbẹ Onikumọ (NNA) ṣe fun awọn adibo. Ohun ti o wa ninu ileri na ko yatọ si ti ironu awọn oṣelu ti o ba ti bọrẹlẹ.

O YA wa lẹnu pe awọn ẹgbẹ Onikumọ yi le ro wipe awọn le mu awọn adibo ni omuzọ. Nwọn ti gbagbe pe bi awọn adibo ko bii ti ṣe ọdẹ ri, nwọn mọ ẹsẹ koi ti lọ.

AWỌN adibo Ipinlẹ Iwọ Orun ti dan ẹgbẹ Afẹnifẹre wo, nwọn si ri itura ati ifọkanbalẹ. Awọn adibo kanna ti dan ẹgbẹ Akintọla wo, nwọn ba ara wọn ninu oko ẹru iponju, alafiafiti ati aifọkanbalẹ. O ha le ya ẹnikẹni lẹnu bi awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun ba nrahun lojojumọ fun ipadabọ ẹgbẹ Afẹnifẹre lati wa ra wọn pada kuro loko ẹru awọn ọdalẹ ati jẹguduragudu oṣelu?

NIGBATI ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA) gbe ileri ti wọn jade, aiye gbọ, orun mọ ohun ti nwọn fẹ ṣe tati ṣe aṣeyege awọn ileri na tabi ọna ti nwọn yio gba mu ileri na ṣe. Kilo ṣẹlẹ nipa ti ẹgbẹ Onikumọ (NNA)? Nwọn fọ oyinbo on yangi bi ẹnipe oyinbo fifọ ni yio bọ awọn enia ti ebi npa, ti awọn enia ti awọn jẹunjẹun oṣelu ti sọ di ẹdun arinlẹ yio tun dide,

KI iṣe ileri ti ko ni ṣe muṣe ni awọn adibo nfẹ. Nwọn nfẹ ijọba ti ko ni fi ebi pa wọn, ti ko ni yi aṣọ wọn pada si bi ti aparo. Ẹniti o ba de Ipinlẹ Iwọ Orun ni yio mọ ohun ti oju awọn enia Ipinle na nri lọwọlọwọ. Ọgba awọn Agodi ko ti fẹrẹ kun akunya? Ki lo fa? On nu-un. Ẹgbẹ Dọmọnu kanna lo mbẹbẹ fun ibo awọn enia lori ileri asan. Ẹniti o ba dibo fun ileri asan ko ni ṣai da ara rẹ lẹbi lẹhinwa ọla.

EGBAAGBEJE awọn enia ni o nrin igboro kakiri laini iṣẹ ṣe, bawo ni ẹgbẹ Onikumọ ṣe fẹ pese iṣẹ fun wọn? Iponju aje ti o wa kakiri orilẹ ede yi yẹ fun akiyesi ẹgbẹ Onikumọ. Bawo ni nwọn ṣe fẹ yanju rẹ?

A MỌ wipe ẹgbẹ Onikumọ fẹ lu awọn adibo ni jibiti ni ṣugbọn ọmọ ti o ba sọ pe iya on ko ni sun, on na ko ni foju ba orun.

## Ilana yẹyẹ

Ẹka ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Ipinle Ila Orun sọ ni ilu Aba ni ojo Ọjọ'Ru ti ise ojo kerin oşu yi pe ilana ohun ti egbe Onikumo NNA so pe on ni nipamo fun awon enia orileede yi je ilana ti ko nilari rara o si je ilana yẹyẹ patapata gba ti ko le wu enikeni lori.

Ninu ikede kan ti egbe Afenifere gbe jade ni ilu Aba ni ojo na, egbe na so pe ilana na dabi owuru ọrọ asan ti o njade lati enu awon oselu ti nwọn ti borele ninu oro iselu.

Ẹka egbe Afenifere na se alaye pe ilana na ki iṣe ogede iro funfun nikan, ṣugbọn o tun je ona jibiti lati le mu ki awon enia orileede yi gba ohun ti ko le seese lailai ni orileede yi gbo.

Egbe Afenifere na fikun pe gbogbo awon ileri ti o wa ninu ilana na tile jina tefetefe si ohun ti egbe Olomi ati egbe Domonu nse lọwọlọwọ bayi ni awon Ipinle Ariwa ati Iwo Orun nibiti nwon ti nse akoso ijoba lode oni.

Ẹka egbe na ni Iha Ila orun tesiwaju wipe ohun ti awon enia orileede yi fe mo ni koko awon ohun giriki ti ọkọkan ninu awon egbe ti nwọn parapo di egbe Onikumo NNA ti ṣe tẹlẹ ri, ki Iṣe pe ki enia ma fonnu pelu ọrọ didun ti o kun fun itanje ati iro ni awon enia nfe gbo.

### SEGESEGE

Ẹgbe Afenifere so pe niwon igbati egbe Onkumo ba ti le pi ogbologbo iro ti ko bo won lehin ese bawonyi, ewu nlanla gan ni yio je ti awon enia orileede yi ba sesi gbe igbesi aiye won le iru egbe be lowo nipa didibo fun won wole.

* Ẹka egbe Nigeria Elements Progress Union NEPU ti Ipinle Ila Orun so wipe yi pe ilana ohun ti egbe Onikumo-NNA ni nipamo

(Wo oju ewe kẹjọ)

## 'Ọmọ Odua' de

IROHIN YORUBA tun gbe de o! 'Ọmọ Oduduwa' na ti e ti nreti, o de!

Ologini tajo de, ki ekute ile parapa.

Ka IROHIN YORUBA ni ọsẹ ti o mbọ fun awari 'Ọmọ Oduduwa' lori oye Are Ọna kakanfo.

Iru oye wo ni Are Ọna kakanfo? Kini itan Yoruba wi nipa rẹ?

Ṣoki ni ọbẹ ọmọge. Irohin ko ni to afojuba.



ALHAJI D. S. ADEGBENRO

## Dibo fun UPGA ki Naijiria dọkan

—OKPARA

Dokita Michael Okpara, Olotu Ipinle Ila Orun ti o tun je okan ninu awon asiwaju fun apapo ẹgbẹ Alakuko, Ọlọpẹ ati oniranwo ti oruko apapo won nje 'UPGA' so nibi ipade ita gbangba ti o ṣe ni ilu Jos ni Oke Oya ni ojo Ru ti iṣe ojo kẹrin osu kokanla yi pe bi apapo egbe na ba gba Ijoba Apapo

(Wo oju ewe kẹjọ)

